Language: Yorùbá

# Ìlò òwe akọni D.O. Fágúnwà nínú ìwé ìtàn àròsọ *ògbójú ọdẹ nínú igbó irúnmọlẹ̀*

**Raphael Ayodeji ADESUYAN (Prof.)**
Department of Yorùbá, Adeyemi Federal University of Education, Ondo, Nigeria
E-mail: radesuyan1@gmail.com
ORCID iD https://orcid.org/0009-0006-2088-9136

&

**Taofiq SA'ADU (Dr.)**
Department of Yorùbá, Adeyemi Federal University of Education, Ondo, Nigeria
E-mail : taofiqsaadu@gmail.com
ORCID iD https://orcid.org/0009-0000-1708-2805

**ÀṢAMỌ̀**

Ohun tí iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí dá lé lórí ni àwọn òwe inú ìwé ìtàn àròsọ *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀* (*Ògbójú*, láti ìsisìyìí lọ) tí akọni òǹkọ̀wé Daniel Ọlọ́runfẹ́mi Fágúnwà kọ. Ohun tó sì jẹ wá lógún ni ṣíṣe àfihàn pàtàkì àti ìlò wọn gẹ́gẹ́ bí ohun èlò ajẹmọ́ èdè, àṣà àti ọ̀nà ìgbàsọ̀tàn nínú ìwé *Ògbójú*. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀, ní àwùjọ Yorùbá àti ilẹ̀ Adúláwọ̀ lápapọ̀, òwe ni kókó nínú ìbáraẹnisọ̀rọ̀, ojú àmúwayé àti àmúlò fún ìsọ ajẹmọ́ ọgbọ́n, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àti ìwà-ẹ̀tọ́ láàrin àwùjọ. Nínú *Ògbójú*, àwọn òwe wọ̀nyí jẹ́ ohun èlò pàtàkì tó mú kí ó jẹ́ gbajúgbajà òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ. Ìṣọwọ́lò àwọn òwe wọ̀nyí ló sì mú kí Fágúnwà di akọni òǹkọ̀wé Yorùbá láwùjọ àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀. Tíọ́rì àmúlò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí jẹ́ ti ọlọ́pọ̀ ìmọ̀. Àkọ́kọ́ ni tíọ́rì tó jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa ìrísí, ìtumọ̀, orísun, ìpínsísọ̀rí, ìhun àti ìwúlò wọn. Èkejì ni tíọ́rì ajẹmọ́ àṣà alohùn tó níí ṣe pẹ̀lú àmúlò àwọn òwe nípa ìlànà àtẹnudẹ́nu dípò àkọsílẹ̀. Tíọ́rì kẹta ni èyí tó ń ṣàlàyé ohun gan-an tí òwe ń ṣe nínú ìsọ yàtọ̀ sí ìtumọ̀ rẹ̀ lérèfé. Èyí fún wa ní òye nípa ìgbéayé ènìyàn, àyànmọ́, ìgboyà, ìwà-ẹ̀tọ́, ipò àwọn àgbà láwùjọ, ìkìlọ̀, ìmọ̀ràn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọgbọ́n ìwádìí tí a mú lò fún iṣẹ́ yìí ni ṣíṣe àkójọ àwọn òwe inú *Ògbójú*. A óò ṣe àlàyé nípa bí D.O. Fágúnwà ti ṣe àmúlò wọn, èyí tí ó mú kí ìwé náà jẹ́ gbajúgbajà láàrin àwọn ìwé ìtàn àròsọ D.O. Fágúnwà àti àwọn ìwé ìtàn àròsọ mìíràn ní ilẹ̀ Adúláwọ̀. A óò wo iṣẹ́ àtinúdá nípa àmúlò òwe tí Fágúnwà ṣe tó mú kí ó jẹ́ akọni òǹkọ̀wé lágbàáyé. A kò ṣàìní wá àwọn ìwé ìtàn àròsọ mìíràn àti átíkù tó dá lórí òwe àti ìwúlò wọn láwùjọ. Wọn yóò ràn wá lọ́wọ́ láti lè ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí tẹ́rùn. Àbájáde iṣẹ́ yìí jẹ́ ká ní ìmọ̀ nípa oríṣìíríṣìí òwe Yorùbá tó wà nínú *Ògbójú* àti ìwúlò wọn, èyí tó mú kí ìwé *Ògbójú* ó gbayì. Ó tún túbọ̀ fikún ìmọ̀ wa nípa òwe Yorùbá bí ó ti ṣe kan, ìrísí, oríṣìí, ìhun àti ìlò wọn nípa àṣà, ìṣe àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá.

**KÓKÓ-Ọ̀RỌ̀**

Òwe, Fágúnwà, Ìtàn-Àròsọ, Ògbójú-Ọdẹ, Irúnmalẹ̀.

**O uso do provérbio "Akoni d.o. Fágúnwà" na história "Ogbogu Odey", na floresta da selva**

**RESUMO**
O tema deste artigo são os provérbios presentes na obra *Ogbojou Odê nínú Igbó Irúnmale* (doravante denominada *Ogbojou*), escrita por Daniel Olorunfemi Fágúnwa. Nosso objetivo é destacar a importância e o emprego desses provérbios como recursos linguísticos, culturais e retóricos na obra. Como é sabido, na sociedade iorubá e no continente africano em geral, os provérbios constituem a base da comunicação, servindo como meio de expressão e veículo para transmitir sabedoria, conhecimento e valores morais à comunidade. Em *Ogbojou*, tais provérbios são um elemento fundamental que contribuiu para a popularidade do autor. O uso dessas expressões consagrou Fágúnwa como uma figura de destaque na literatura iorubá entre seus pares. A abordagem teórica adotada para esta análise é multifacetada. A primeira vertente teórica concentra-se no estudo da forma, significado, origem, distribuição, conteúdo e uso dos provérbios. A segunda aborda a tradição oral, analisando como os provérbios são empregados oralmente, em contraposição à forma escrita. A terceira teoria explica a função do provérbio no discurso para além de seu sentido literal, proporcionando uma compreensão sobre a vida humana, o destino, a coragem, a moralidade, o papel dos anciãos na sociedade, bem como sobre advertências, conselhos, entre outros aspectos. A metodologia de pesquisa consiste em compilar os provérbios presentes em *Ogbojou*. Examinaremos a maneira como D.O. Fágúnwa os utilizou — fator que conferiu grande popularidade à obra, tanto em relação aos demais livros do autor quanto no contexto literário do continente africano — e analisaremos a criatividade de Fágúnwa no emprego desses provérbios, o que o projetou como um escritor de renome mundial. Também analisaremos outras obras e artigos que abordam provérbios e seu uso social, subsidiando assim a análise proposta neste artigo. Os resultados deste trabalho permitem ampliar o conhecimento sobre os diversos provérbios iorubás presentes em *Ogbojou* e suas funções, elementos que contribuíram para o sucesso da obra. Além disso, o estudo aprofunda a compreensão dos provérbios iorubás no que tange à sua forma, variedade, conteúdo e aplicação, relacionando-os à cultura, às práticas e às crenças do povo iorubá.

**PALAVRAS-CHAVE**
Provérbios, Fágúnwá, Ítán-Áróśó, Ógbojú-Ódé, Irúnmale.

**The use of the proverb "Akoni d.o. Fágúnwà" in the story "Ogbogu Odey" in the forest of the jungle**

**ABSTRACT**
This paper examines the use of proverbs by the legendary author, Daniel Ọlọ́runfẹ́mi Fágúnwà in his classic work, *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀* (The Forest of a Thousand Daemons) (*Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀* will henceforth be referred to as *Ògbójú* in this paper). Our main concern in this work is to show the significance and functions of these proverbs as linguistic, cultural and narrative devices in the novel. Proverbs are central to Yorùbá communication and worldview, functioning as concise expressions of communal wisdom and moral philosophy. The proverbs serve as tools for conveying meaning. Fagunwa's story-telling technique sets him aspart from other authors, which earned him wide fame and solidified his status as legendary writer.

Theories adopted are paremiology, oral tradition and functional stylistics to show how these proverbs operate within the text. Paremiology studies the form, meaning, source, classifications and functions of proverbs. Oral tradition is about how knowledge and cultural values are transmitted through spoken forms such as folktales, myths, song and proverbs. Functional stylistics studies how language functions in literary texts to produce meaning and aesthetic effects. Methodology adopted includes collection of proverbs in *Ògbójú*, examining how each proverb functions within specific narrative situations. We would look into Fagunwa's works that also made him to be a legendary writer. Other works and articles on proverbs would be looked into for deeper analysis of these proverbs. This work enriches our knowledge more on forms, types, structures and functions of proverbs on Yorùbá culture, belief and philosophy.

**KEYWORDS**
Proverb, Fágúnwà, Novel, Brave-Hunter, Daemons.

**Tíọ́rì Àmúlò**

Àwọn onímọ̀ kò kó iyán tíọ́rì kéré nínú iṣẹ́-ọnà bí ó ti wù kí ó mọ. Tíọ́rì ni àgbékalẹ̀ èrò tó jinlẹ̀ nípa ohunkóhun lẹ́yìn àwòfín àti ẹ̀rí tó dájú. Ó jẹ́ àlàyé nípa nǹkan, èyí tó ṣe é gbẹ́kẹ̀lé. Tíọ́rì tí a fẹ́ẹ́ mú lò fún iṣẹ́ yìí ni ti ẹ̀kọ́ tó jẹ mọ́ òwe nípa ìrírí, ìtumọ̀, ìhun, orísun, ìlò ajẹmọ́ èdè àti àṣà àti ògbufọ̀ wọn. Ó jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa ìlò nínú ìbáraẹnisọ̀rọ̀ nípa ẹ̀kọ́, ìkìlọ̀, ìmọ̀ràn abbl. Agbátẹrù tíọ́rì yìí ni Mieder (2004), tó rí òwe gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ ṣókí tí a fi sọ òkodoro ọ̀rọ̀. Tíọ́rì yìí ràn wá lọ́wọ́ nínú àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí.

Tíọ́rì kejì ni ti lítíréṣọ̀ alohùn tó níí ṣe pẹ̀lú ìlò òwe ní ìlànà àtẹnudẹ́nu dípò kíkọ sílẹ̀. Èyí jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn ènìyàn àwùjọ ń gbà ṣe ohun ìní wọn lọ́jọ̀ kí ó má ba parun. Ìlànà àtẹnudẹ́nu ni wọ́n ń lò láti ìran kan sí òmíràn. Èyí hàn nínú *Ògbójú* nípa ìlànà àwítúnwí àti ìtàn sísọ láti ẹnu àwọn àgbà. Finnegan (1970) ni agbátẹrù rẹ̀.

Tíọ́rì kẹta ni èyí tó jẹ mọ́ iṣẹ́ tí à ń fi òwe ṣe gan-an nínú àyọkà yàtọ̀ sí ìtumọ̀ eréfèé rẹ̀. Ó tẹpẹlẹ mọ́ iṣẹ́ òwe àti èrèdí lílò rẹ̀ bó ti ṣe jẹ mọ́ ìgbéayé ènìyàn, àyànmọ́, ìwà ẹ̀tọ́, ojúṣe àgbàlagbà, ìkìlọ̀, ìmọ̀ràn, ìwà àìtọ́ láwùjọ bíi ojúkòkòrò, àìnítẹ̀lọ́rùn abbl. Agbátẹrù rẹ̀ ni Halliday (1978).

**Ọgbọ́n Ìṣèwádìí**

Ọgbọ́n ìṣèwádìí tó jẹ mọ́ ìlànà àtúpalẹ̀ inú àyọkà tó péye ni a lò láti ṣe àyẹ̀wò àwọn òwe ìwé *Ògbójú*. Ó fún wa ní àǹfààní àtúpalẹ̀ tó jinlẹ̀ lórí ìwúlò òwe tó jẹ mọ́ èdè, àṣà àti ìṣọwọ́lò-èdè nínú ìwé *Ògbójú*. A óò ṣe àwárí àti àfihàn gbogbo àwọn òwe ìwé *Ògbójú*. A óò wo ìtumọ̀ àti ìlò wọn ní ọ̀gangan ipò tí a ti lò wọ́n. *Ògbójú* ni orísun àkọ́kọ́ fún àkójọpọ̀ èdè fáyẹ̀wò wa. Òmíràn ni àwọn ìwé lítíréṣọ̀ Yorùbá, átíkù, iṣẹ́ àtẹ̀yìnwá tí Fágúnwà ti ṣe. A óò ṣe àkójọpọ̀ àwọn òwe inú *Ògbójú* bí wọ́n ṣe ṣe kókó sí. Àtúpalẹ̀ wọn yóò jẹ mọ́ kókó àti iṣẹ́ wọn.

**Ìfáárà**

Iṣẹ́ àpilẹ̀kọ lórí òwe Yorùbá jẹ́ èyí tí àwọn onímọ̀ ti ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀ káàkiri ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ bí fọ́kìlọ̀ọ̀, ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, ẹ̀kọ́ ìtàn àti lítíréṣọ̀ bíi Délànọ̀ (1966), Bámgbóṣé (1968), Finnegan (1970), Beier (1967), Owólabí (2001) abbl. Ní àwùjọ Yorùbá àti ilẹ̀ Adúláwọ̀, òwe jẹ́ ohun èlò pàtàkì fún ṣíṣe àtaré àṣà, ìṣe àti ìgbàgbọ́ wọn láti ìran dé ìran. Òwe jẹ́ kókó fún ìbánisọ̀rọ̀ àti ọgbọ́n ojoojúmọ́ láàrin wọn. Èyí ló bí òwe, "Òwe lẹṣin ọ̀rọ̀; bí ọ̀rọ̀ bá sọnù, òwe la fi í wá a". Ó ṣe pàtàkì nínú lítíréṣọ̀

àtẹnudẹ́nu àti alákọsílẹ̀. Ọ̀pọ̀ òǹkọ̀wé ló ti ṣe àmúlò òwe nínú iṣẹ́ wọn, yálà ìtàn àròsọ, eré-oníṣe àti ewì. Lára wọn ni Fágúnwà (1938; 1949; 1954 àti 1961), Fálétí (1970), Òkédìjí (1971), Ìṣọ̀lá (1983) abbl. *Ògbójú* ni èyí tí iṣẹ́ yìí dá lé lórí, tó sì jẹ́ ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀ àkọ́kọ́. Àwọn onímọ̀ ti ṣe iṣẹ́ akadá jìnnà lórí àwọn òwe Fágúnwà, ṣùgbọ́n ìlò òwe nínú iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ kókó, èyí tí a sì fẹ́ẹ́ gbé yẹ̀ wò. A ṣe àtúpalẹ̀ oríkì, ìrísí, orísìí, ìtumọ̀, ìhun àti ìlò àwọn òwe nínú *Ògbójú*. Ọgbọ́n ìwádìí tí a lò jẹ́ kí á ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ òye òwe tó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣọwọ́lò-èdè nínú *Ògbójú*.

Nínú iṣẹ́ yìí, a wo ẹni tí akọni òǹkọ̀wé D.O. Fágúnwà jẹ́ àti ìwé ìtàn àròsọ *Ògbójú*. A ṣe àkójọpọ̀ àwọn òwe inú rẹ̀. Kókó tí àwọn òwe wọ̀nyí jẹ mọ́ ni ìmọ̀ràn, ìkìlọ̀, fífi ẹ̀mí ìmoore hàn, ìṣítí àti ìbáwí. Iṣẹ́ yìí fi kún ìmọ̀ nípa pípèsè àtúpalẹ̀ alákòóyawọ́ ìlò àwọn òwe nínú *Ògbójú*. A ṣe èyí nípa àmúlò tíọ̀rì ìgbàlódé fún ṣíṣe àlàyé tó jinlẹ̀ lórí iṣẹ́ òwe bí kókó ìtàn àròsọ. Èyí ṣe àfihàn Fágúnwà bí òǹkọ̀wé tó lo ìmọ̀ rẹ̀ nínú àṣà, ìṣe, ìgbàgbọ́ àti ìrírí rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ àti ẹlẹ́sìn Kírísítì hàn. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, ìbánisọ̀rọ̀ tààrà, ìtàn nínú ìtàn, ète àlá àti ìtọ́ka síwájú àti sẹ́yìn nínú *Ògbójú* mú kí Fágúnwà yàtọ̀ sí àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀, èyí tó mú kó jẹ́ akọni òǹkọ̀wé.

**D.O. Fágúnwà àti *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀***

A bí D.O. Fágúnwà ní ọdún 1903. Oròwọlé ni orúkọ àbísọ rẹ̀ kí ó tó yí i padà sí Ọlọ́runfẹ́mi ní kété tí àwọn òbí rẹ̀ di ẹlẹ́sìn Kírísítì. Ìlú Òkè-Igbó ni ó ti lọ sí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní ọdún 1916-1924. Ó kọ́ ẹ̀kọ́ olùkọ́ni ní St. Andrew's College, Ọ̀yọ́ ní ọdún 1926-1929. Ó ṣiṣẹ́ olùkọ́ ní oríṣiríṣi ìlú kí ó tó gba iṣẹ́ ní ilé iṣẹ́ ìtẹ̀wé Heinemann ní Ìbàdàn. Ó kọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwé ìtàn àròsọ àti àwọn ìwé mìíràn nínú èyí tí *Ògbójú* jẹ́ ọ̀kan, tó sì jẹ́ àkọ́kọ́. Ó kú ní ọjọ́ keje, oṣù kejìlá, ọdún 1963 sínú Odò-Ọya ní Baro (Olújìnmí, 2011; Adébọ̀wálé, Adélékè àti Adéjùmọ̀, 2016). Ọmọ ọ̀dọ̀ àgbà ni Fágúnwà. Inú ìjìnlẹ̀ àṣà Yorùbá ní Òkè-Igbó ni a bí i sí. Ó gbọ́ èdè Yorùbá dáradára. Ó mọ òwe, ó sì lò ó bó ti tọ́ àti bó ti yẹ nínú *Ògbójú* àti àwọn iṣẹ́ rẹ̀ mìíràn gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ èdè ṣe jẹ́rìí sí i (Beier, 1965 àti 1967; Liindfors, 1982; Bámgbóṣé, 2007a àti 2007b, Irele 1981, Òjó 2015). Wọ́n rí D.O. Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí ẹni tó máa ń hun òwe pọ̀ mọ́ ìtàn àròsọ rẹ̀. Wọ́n tún rí i bí ẹni tó ń lo òwe ní ìgbà àti àsìkò tó yẹ pẹ̀lú àwọn ọnà-èdè mìíràn bíi àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ àti àwòrán ọ̀rọ̀. Ìrírí rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ojúlówó ọmọ Yorùbá, àwùjọ tó gbé dàgbà, iṣẹ́ olùkọ́ tó ṣe, ẹ̀sìn Kírísítì tó gbà àti àwọn ìwé tó kà ni wọ́n ràn án lọ́wọ́ láti tayọ ju àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀ lọ nínú ìwé ìtàn-àròsọ kíkọ àti ṣíṣàmúlò òwe. Èyí ló jẹ́ kí ó di akọni òǹkọ̀wé láwùjọ Yorùbá, ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti ní àgbáyé. Bámgbóṣé (2007a) sọ pé Fágúnwà ni ẹni àkọ́kọ́ nínú ẹ̀kọ́ ìtàn àròsọ ní èdè Yorùbá. Ṣáájú rẹ̀ kò sí ẹnikẹ́ni, lẹ́yìn rẹ̀ kò sí bákan náà. Aṣáájú tí àwọn òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ Yorùbá ń tọ̀ lẹ́yìn ni.

*Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀ (The Brave Hunter in the Forest of a Thousand Spirits (or Deities*)) jẹ́ ìwé ìtàn-àròsọ ilẹ̀ Adúláwọ̀ tó gbajúgbajà, tí a tẹ̀ jáde ní ọdún 1938. Ṣóyínká ṣe àtẹ̀jáde rẹ̀ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì ní ọdún 1968, tí àtúntẹ̀ rẹ̀ jáde ní 2013, èyí tí ó mú kí àwọn òǹkàwé yìí pọ̀ si jákèjádò àgbáyé. *Ògbójú* jẹ́ ìwé ìtàn-àròsọ tó ṣàpèjúwe Àkàrà-ogùn gẹ́gẹ́ bí ọdẹ tó gbójú gbóyà, tó rin ìrìnàjò sí igbó burúkú níbi tí àwọn abàmì ènìyàn, ẹranko, ẹyẹ àti iwin fi ṣe ibùgbé. Ní gbogbo ìrìnàjò rẹ̀, àwọn abàmì ẹ̀dá wọ̀nyí ló bá pàdé, tí wọ́n sì máa ń wọ ìyá ìjà, ṣùgbọ́n lẹ́yìnòrẹyìn, ó borí, ó sì dé láyọ̀. Akọni ọdẹ ni.

**Àwọn Òwe inú *Ògbójú* àti Àtúpalẹ̀ wọn**

Àpẹẹrẹ 1:
Bí e̅gun ẹni bá jo̅re, orí a yá ni (o.i. 1)
(Bí eégún ẹni bá jóore, orí a yáni)

Òwe ìmọ̀ràn lèyí láti máa ṣe ohun tó tọ́. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí láti mú kí olùgbọ́ ìtàn rẹ̀ pa gbogbo ohun tí wọ́n ń ṣe tì láti gbọ́ ìtàn tí ó fẹ́ẹ́ sọ. Eégún jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn irúnmalẹ̀ ní àwùjọ tí wọ́n ń bọ ní ìrántí baba tó kú, tí ó sì máa ń jó tí wọ́n bá gbé e jáde. Tí ó bá jó dáadáa, inú atọ́kùn àti àwọn òǹwòran yóò dùn, tí kò bá sì jó dáadáa, inú wọn kò níí dùn. Èyí ń kọ́ wa pé kí a máa hùwà dáadáa kí a ba lè rí ojúrere àwọn ènìyàn gbà.

Àpẹẹrẹ 2
Ọwọ́ ara ẹni ni a mà fi ntun ọ̀ràn ara ẹni ṣe (o.i. 9-10)
(Ọwọ́ ara ẹni ni a máa fi ń tún ọ̀rọ̀ ara ẹni ṣe)
Híhu ìwà rere láwùjọ jẹ Yorùbá lógún. Èyí jẹ́ ìwà-ẹ̀tọ́. Àìhùwà rere kì í jẹ́ kí ènìyàn bá ojú rere pàdé tàbí kó rí àánú gbà. Òwe yìí jẹ́ òwe ìmọ̀ràn pé kí ènìyàn hu ìwà rere, kí ó pa ìwà burúkú tì. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí nígbà tí ó ń wá ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ iwin tí kò jẹ́ kó rẹ́ran pa. Ṣáájú ni Àkàrà-oògùn ti sọ òkò ọ̀rọ̀ síi. Òun náà sì fèsì padà si pé oníbàjẹ́ ènìyàn ni. Ṣùgbọ́n, ó padà bẹ iwin yìí kí ó ṣe òun lóore, ó sì gbọ́ ẹ̀bẹ̀, ó sì ṣe é lóore kó tó lọ.

Àpẹẹrẹ 3
Yọyọ ni ẹni araiye ndà (o.i. 10-11)
(Yọ̀yọ̀yọ̀ lẹnu ọmọ aráyé)
Òwe yìí ni ẹbọra Aládé-Igbó pa fún Àkàrà-oògùn nípa bí àwọn ènìyàn ṣe ń fi ẹnu wọn sọ ohun tó dára àti èyí tí kò dára nípa ènìyàn tàbí ohunkóhun. Òwe ìkìlọ̀ lèyí pé ká ṣọ́ra fún ènìyàn, kí a má sì gbẹ́kẹ̀lé ènìyàn.

Àpẹẹrẹ 4
Ẹniti o ṣe ohun ti ẹnikan kò ṣe rí, oju rẹ̀ nã yío ri nkan ti enikan ko rírí (o.i. 21-22)
(Ẹni tí ó ṣe ohun tí ẹnìkan kò ṣe rí, ojú rẹ̀ yóò rí nǹkan tí ẹnìkan kò rí rí)
Òwe ìkìlọ̀ lèyí pé kí a ro ìgbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ kí a tóó dáwọ́lé ṣíṣe ohunkóhun kí a má ba kábàámọ̀ nípa rẹ̀. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí nígbà tó fẹ́ẹ́ bẹ̀rẹ̀ ìtàn sísọ lórí ìgbà èkejì rẹ̀ nínú igbó irúnmalẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó jìyà ní ìgbà àkọ́kọ́ nínú igbó, síbẹ̀, ó tún pinnu láti lọ lẹ́ẹ̀kejì.

Àpẹẹrẹ 5
Ọpẹ́lọpẹ́ ejika ti kò jẹki ẹwu k’o bọ (o.i. 29)
(Ọpẹ́lọpẹ́ èjìká tí kò jẹ́ kí ẹ̀wù kó bọ́)
Òwe fífi ẹ̀mí ìmoore hàn lèyí. Èjìká ni ẹ̀yà ara tí kì í jẹ́ kí aṣọ tí a bá wọ̀ já lọ́rùn ẹni. Bí a bá ṣeni lóore, ọpẹ́ ló yẹ kí a dá. Ìyàwó Ọba ló pa òwe yìí láti fi tàbùkù ọba tó jẹ́ ọkọ rẹ̀ lójú àwọn ará ìlú pé kì í tọ́jú òun. Ó fi hàn pé ìyá òun ló ń ṣe gbogbo ohun tí ó yẹ kí ọba ṣe fún òun.

Àpẹẹrẹ 6
Ẹniti o ba da ẽru ni ẽru itọ̀ (o.i. 30)
(Ẹni tí ó bá da eérú ni eérú ń tọ̀)
Òwe ìkìlọ̀ pé kí á ta kété sí ìwà ìkà sí ọmọnìkejì wa nítorí pé ẹni bá pète ibi, bópẹ́ bóyá, ibi yóò padà wá bá irú ẹni bẹ́ẹ̀. Ìyàwó ọba tó gbìmọ̀ ibi pọ̀ pẹ̀lú àwọn ará ìlú láti pa ọba (ọkọ rẹ̀), òun gan-an ni àwọn ìránṣẹ́ ikú pa láìmọ̀.

Àpẹẹrẹ 7
Ajẹ ke lana ọmọ ku loni, tani kò mọ̀ pe ajẹ ana lo pa ọmọ jẹ (o.i. 35)
(Àjẹ́ ké lánàá, ọmọ kú lónìí, ta ni kò mọ̀ pé àjẹ́ àná ló pọmọ jẹ)

Yorùbá ní ìgbàgbọ́ ní ẹ̀mí àjẹ́. Tí àjẹ́ kan bá pariwo tàbí bá ẹnìkan jà ní agboolé kan ní àná, tí ọmọ kan sì fò ṣánlẹ̀ kú ní inú agboolé náà ní ọjọ́ kejì, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé, kò sí àníàní, àjẹ́ tí ó ké ní àná ni ó pa ọmọ jẹ. Òwe ìkìlọ̀ ni èyí jẹ́ láti tẹ̀ mọ́ ẹni bẹ́ẹ̀ létí kí ó rọra ṣe nítorí bí ohunkóhun bá ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn ìbínú rẹ̀, ó dájú pé òun ni wọn yóò fi irú ọ̀ràn bẹ́ẹ̀ kọ́ lọ́rùn. Òwe yìí wúlò fún fífi ìdí ohun tí a lérò pé ẹnìkan ṣe múlẹ̀. Ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí láti fihàn pé Àkàrà-oògùn ló jí ajá ọba tó sọnù. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé lẹ́yìn ò rẹyìn, ó hàn pé irọ́ ló pa.

Àpẹẹrẹ 8
Labalaba ti o ba digbo lu ẹgun aṣọ rẹ̀ yio faya (o.i. 36)
(Labalábá tí ó bá dìgbò lu ẹ̀gún, aṣọ rẹ̀ yóò fà ya)
Kòkòrò tó ń fò ni labalábá, tí aṣọ rẹ̀ sì máa ń fúyẹ́ débi pé tí ó bá dìgbò tàbí kọ lu ẹ̀gún, yóò ya ni, kò sì níí sí èyí tí yóò fi máa fò mọ́. Òwe ìkìlọ̀ ni èyí kí ènìyàn rọra ṣe, nínú ohunkóhun kí ó má ba kábàámọ̀. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí nígbà tí ó ṣetán láti pa ọ̀rẹ́ rẹ̀ tó parọ́ mọ́ ọn.

Àpẹẹrẹ 9
Ọpọlọpọ alangba ni o da ikùn de ilẹ a ko mọ eyiti inu nrun (o.i. 48)
(Ọ̀pọ̀lọpọ̀ aláǹgbá ni ó da ikùn dé ilẹ̀, a kò mọ èyí tí inú ń run)
Òwe ìkìlọ̀ ni èyí jẹ́ pé kí ènìyàn rọra ṣe nítorí ọ̀pọ̀ ènìyàn ni wọ́n máa ń ṣe bí ọ̀rẹ́ síni, ṣùgbọ́n tí wọ́n jẹ́ ìkà ènìyàn tí wọ́n sì lè ṣebi síni nígbàkúùgbà. Ó ṣòro láti mọ èrò ènìyàn. Èyí ni Àkàrà-oògùn fi wé aláǹgbá tó ń da àyà délẹ̀ ní gbogbo ìgbà, tí kò sì rọrùn láti mọ èyí tí inú ń run láàrin wọn. Ó pa òwe yìí láti fi gba àwọn tó wá gbọ́ ìtàn tó fún fẹ́ẹ̀ sọ nípa àwọn èrò Òkè Láńgbòdó níyànjú.

Àpẹẹrẹ 10
Bi ọmọde ni aṣọ bi agba ko ni ile ni akisa bi agba (o.i. 50)
(Bí ọmọdé bá láṣọ bí àgbà, kò lè ní àkísà bí àgbà)
Òwe yìí ń ṣe àfiwé ọmọdé àti àgbàlagbà nípa ìrírí, ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye. Èyí fi hàn pé ìrírí, ọgbọ́n, ìmọ̀ àti làákàyè àwọn àgbàlagbà ju ti ọmọdé lọ. Àgbàlagbà ló ṣàgbà ọmọdé. Ó jẹ́ ìmọ̀ràn fún ọmọdé kó má rí àgbà fín bíí ti wù ó mọ. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí láti fèsì sí ìpàrọwà ọba sí i láti lọ sí Òkè Láńgbòdó.

Àpẹẹrẹ 11
Bi ina ko ba tan laṣọ ẹjẹ ko le tan lekan (o.i. 52)
(Bí iná kò bá tán láṣọ, ẹ̀jẹ̀ kò lè tán léékán)
Òwe ìmọ̀ràn láti má káàárẹ̀ tàbí fàsẹ́yìn lórí ohunkóhun lèyí. Ọwọ́ la fi ń mú iná orí tí a óò sì fi èékánná pa á. Tí a bá pa á, ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ á ṣàn sí èékánná. Ó dìgbà tí iná náà bá tán lórí kí mímú àti pípa rẹ̀ tóó tán. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí sí Kàkó láti ṣe ìpinnu láti lọ sí Òkè Láńgbòdó.

Àpẹẹrẹ 12
Ki ilẹ to pa òṣìkà, ohun rere yio ti bajẹ (o.i. 54)
(Kí ilẹ̀ tó pa òṣìkà, ohun rere yóò ti bàjẹ́)
Òwe ìkìlọ̀ lèyí. Ó túmọ̀ sí pé kí ènìyàn tètè gbé ìgbésẹ̀ lórí nǹkan tó bá yẹ, kí ohun tó dára má ṣe bàjẹ́. Èyí ni òwe tí Kàkó pa nígbà tí ìyàwó rẹ̀ dì í mú nígbà tí ó ń tẹ̀lé Àkàrà-oògùn padà sí ìlú wọn ní ìgbaradì fún lílọ sí Òkè Láńgbòdó. Ó rí obìnrin yìí gẹ́gẹ́ bí ẹni tí kò fẹ́ẹ́ jẹ́ kí òun lọ. Ó pa obìnrin yìí kí ó ba lè tètè tẹ̀lé Àkàrà-oògùn.

Àpẹẹrẹ 13
Ọwọ meji ni igbe ẹru de ori, ọmọ ika ọwọ mararun ni si igbe onjẹ de ẹnu (o.i. 57)
(Ọwọ́ méjì níí gbé ẹrù dé orí, ọmọ ìka ọwọ́ máràárún ní sì ń gbé oúnjẹ dé ẹnu)
Òwe ìmọ̀ràn lèyí, tó túmọ̀ sí pé ìfọwọ́sowọ́pọ̀ máa ń mú nǹkan rọrùn. Èyí ni pé ẹnìkan ṣoṣo kò lè dá nǹkan ṣe, bí kò ṣe rọrùn láti fi ọwọ́ kan gbé ẹrù dé orí. Bàbá arúgbó kan ló pa òwe yìí nígbà tí ó bá àwọn ọdẹ tó ń lọ Òkè Láńgbòdó sọ̀rọ̀ pé kí wọ́n fi ìmọ̀ ṣọ̀kan kí wọ́n ba lè ṣe àṣeyọri nínú iṣẹ́ takuntakun tí wọ́n gbé lé wọn lọ́wọ́. Ó jẹ́ kí wọ́n mọ pàtàkì ìfọwọ́sowọ́pọ̀.

Àpẹẹrẹ 14
Ohun tí a fi ẹ̀sọ̀ mú kí ibajẹ ohun ti a fi agbara mu ni ile ni lara koko̍ko (o.i. 60)
(Ohun tí a fi ẹ̀sọ̀ mú kì í bàjẹ́, ohun tí a fi agbára mú níí leni lára kokooko)
Òwe ìmọ̀ràn lèyí tó sọ pé kí a ṣe sùúrù nínú ṣíṣe ohunkóhun tí a bá dáwọ́ lé, nítorí ìkánjú a máa ba nǹkan jẹ́. Ohun tí a bá fi sùúrù ṣe máa ń yọrí sáyọ̀. Àkàrà-oògùn ló pa òwe yìí ní kété tí wọ́n gba òmìnira lọ́wọ́ Ẹ̀rù. Orin lásán ni wọ́n fi lé Ẹ̀rù, ẹni tí ìbọn àti ọfà kò ràn.

Àpẹẹrẹ 15
Ẹyin ni o ndi àkùkọ, ọmọde oni si ni baba ọla (o.i. 72)
(Ẹyin ni ó ń di àkùkọ, ọmọdé òní sì ni baba ọ̀la)
Òwe ìṣítí lèyí, tó túmọ̀ sí pé ọjọ́ ọ̀la máa dára, nítorí pé bó pẹ́, bó yá, ẹyin adìẹ òní yóò di àkùkọ. Ó túmọ̀ sí pé kí a ní àforítì. Bákan náà, ó túmọ̀ sí pé kí a má ṣe fi ojú tẹ́ńbẹ́lú ẹnikẹ́ni nítorí pé òní la rí, kò sẹ́ni tó mọ̀la. Ẹni tí a lérò pé kò lè já mọ́ nǹkan lónìí lè di ẹni ńlá lọ́la. Òwe yìí ni Ìrágbèje pa nígbà tí ó ṣetán láti sọ̀rọ̀ nípa àwọn ọmọdé fún àwọn àlejò rẹ̀ (Àkàrà-oògùn àti àwọn yòókù).

Àpẹẹrẹ 16
Ẹniti o gun ọpẹ ti o dorikodo, ohun ti oju wa ni oju iri (o.i. 80)
(Ẹni tí ó gun igi ọ̀pẹ, tí ó dorí kodò, ohun tí ojú wá ni ojú rí)
Òwe ìkìlọ̀ lèyí pé kí ènìyàn kọjú sí ohun tó bá ń ṣe láti dènà ìjàm̀bá. Òkè ni akọ̀pẹ máa ń wò nígbà tí ó bá ń gun ọ̀pẹ, kì í ṣe ìsàlẹ̀ nípa dídorí kodò. Ìtumọ̀ òwe yìí ni pé ibi tí a bá ń lọ ni à á kọjú sí. Ìkòokò ló pa òwe yìí lẹ́yìn tí Àjàtàńlá ti lù ú, tí ó sì tún ní kó di òun padà sínú ẹrù kí ó sì tẹsẹ̀ mọ́ ìrìn láti lọ bá àwọn ẹranko ẹgbẹ́ rẹ̀ tókù níwájú.

Àpẹẹrẹ 17
Ile ni a nwo kí a to sọ ọmọ loruko̩ (o.i. 82)
(Ilé ni à ń wò, kí a tó sọ ọmọ lórúkọ)
Òwe ìṣítí lèyí. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé ìpìlẹ̀ nǹkan ni a máa ń wò kí a tó ṣe ìpinnu lórí irú nǹkan bẹ́ẹ̀. Èyí fi hàn pé ó yẹ kí a wo sàkun ọ̀rọ̀ dáadáa kí a tóó ṣe ìpinnu. Ìrágbèje ló pa òwe yìí nígbà tí ó ń sọ̀rọ̀ lórí àwọn àgbà aláṣejù. Ó ní àṣejù nǹkan kò dára, ẹ̀tẹ́ àti àbùkù ló máa ń fà bá ènìyàn.

Àpẹẹrẹ 18
Ebi ki iwọ inu ki ọran miran tun wọ ibẹ (o.i. 83)
(Ebi kì í wọ inú, kí ọ̀rọ̀ mìíràn tún wọ ibẹ̀)
Òwe ìkìlọ̀ àti ìmọ̀ràn lèyí. Ó túmọ̀ sí pé ọ̀kan ni a máa ń fi sílẹ̀ ṣe òmíràn ní ìbámu pẹ̀lú bí wọ́n bá ṣe ṣe pàtàkì sí. Kìnìún, ọba àwọn ẹranko ló pa òwe yìí nígbà tó ń gba àwọn ẹranko ẹgbẹ́ rẹ̀ nímọ̀ràn láti máa yọ̀ọ̀da ara wọn sílẹ̀ fún pípajẹ.

Àpẹẹrẹ 19
Ọkẹrẹ gun ori iroko oju ọdẹ da (o.i. 88)
(Ọ̀kẹ́rẹ́ gun orí ìrókò ojú ọdẹ dá)
Òwe ìbáwí lèyí. Ó túmọ̀ sí pé ìṣẹ̀lẹ̀ kan ti ṣẹ̀, tí kò sì ní àtúnṣe mọ́. Ó já sí pé ènìyàn ti ṣe ohun tó fẹ́ẹ́ ṣe, ojú rẹ̀ sì ti já a, kò sí àtúnṣe mọ́. Ó ye ká yẹra fún irú nǹkan bẹ́ẹ̀. Ìrágbèje ló pa òwe yìí níbi tí ó ti ń sọ ìtàn fún àwọn ọdẹ ní ilé rẹ̀. Ọkùnrin tó ta ìpá síwájú tó sì ba gbogbo nǹkan tó fi ọgọ́rùn-ún pọ́nùn rà jẹ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.

Àpẹẹrẹ 20
Oṣe ni ipari ẹkun abamọ ni igbẹhin ọran gbogbo (o.i. 88)
(Òṣé níí parí ẹkún, àbámọ̀ níí gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ gbogbo)
Òwe ìkìlọ̀ àti ìbáwí lèyí. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé àbámọ̀ tàbí òṣé ni ó máa ń gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ tàbí ohun tí a kò bá rò jinlẹ̀ kí a tó ṣe é. Ìkìlọ̀ ni pé kí a rò ó dáradára kí a tó ṣe nǹkan, kí a má ba kábàámọ̀. Èyí ni òwe tí bàbá Ìrágbèje pa fún àwọn ọdẹ nípa ìwà ènìyàn. Ó sọ pé àbámọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára àbàwọ́n tó wà lára àwọn ènìyàn, tí kò sì sí ẹni tí ó lè fọ̀ ọ́ mọ́ lára wọn.

Nínú àtúpalẹ̀ àwọn òwe wọ̀nyí, kókó tí wọ́n jẹ mọ́ ni ìmọ̀ràn, ìkìlọ̀, ẹ̀mí ìmoore fífi hàn, ìṣítí àti ìbáwí. Àwọn kókó wọ̀nyí ni Fágúnwà ṣe àgbékalẹ̀ wọn láti lè mú kí àwọn òǹkàwé rẹ̀ mú wọn lò. Èyí yóò mú kí àlàáfíà bá ènìyàn àti àwùjọ lápapọ̀. Ìwà ẹ̀tọ́ máa ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ.

**Àgbálọgbábọ̀**

A ti gbìyànjú láti wo àwọn òwe D.O. Fágúnwà nínú ìwé *Ògbójú*. A wo Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé *Ògbójú*. A wo ìtàn ìgbésíayé rẹ̀. A wo ìwé *Ògbójú* tó jẹ́ ìtàn-àròsọ àkọ́kọ́ tí Fágúnwà kọ. A ṣe àkójọpọ̀ àti àfihàn àwọn òwe inú *Ògbójú*. A wo àwọn ìlò wọn bí ó ti ṣe jẹ mọ́ ìkìlọ̀, ìbáwí, ìmọ̀ràn, ìṣítí, fífi ẹ̀mí ìmoore hàn àti àwọn ìwà ẹ̀tọ́ mìíràn tí wọ́n lè mú àyípadà rere bá ènìyàn àti àwùjọ Yorùbá. A wo ẹ̀kọ́ tí a rí kọ́ nínú wọn. A fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àgbékalẹ̀ ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí Fágúnwà mú lò ló jẹ́ kí ìwé *Ògbójú* ó di gbajúgbajà káàkiri àgbáyé. A tún fi hàn pé iṣẹ́ yìí mú kí Fágúnwà yàtọ̀ sí àwọn òǹkọ̀wé ẹgbẹ́ rẹ̀, èyí tó sọ ọ́ di akọni òǹkọ̀wé lágbàáyé. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí a mọ pàtàkì òwe Yorùbá, tí a sì gbọ́dọ̀ pakítí mọ́ra nípa ṣíṣe àwárí àti àmúlò wọn níbi gbogbo, nígbà gbogbo àti lọ́nà gbogbo. Ohun ìní àwùjọ Yorùbá tí kò gbọdọ̀ kú ni.

**Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí**

Adébọ̀wálé, O. àti D. Adélékè (2021). *Àkọ̀tun Èdè Ìperí Yorùbá (New Yorùbá Metalanguage)*. Ìbàdàn: Graceville Publishers.
Adébọ̀wálé, O. àti D. Adélékè àti A. Adéjùmọ̀ (2016). *Ọ̀tun Ìmọ̀ Nínú Ìtàn-Àròsọ D.O. Fágúnwà (Findings in the Novels of D.O. Fágúnwà)*. Lagos: The Capstone Publications.
Adéyẹmí, L. (2012). "Proverbs and Narrative Meaning in Yorùbá Literature". *Paremia Journal*, 21, 245-256.
Awóbùlúyì, O. àti O.O. Oyèláràn (2017). *Ìléwọ́ Ìkọ̀wé Yorùbá Òde-Òní*. Ìlọrin: Kwara State University Press.
Bámgbóṣé, A. (1968). "The Form of Yorùbá Proverbs". *Odu: A Journal of West African Studies*, 5, 25-32.
Bámgbóṣé, A. (2007a). *The Novels of D.O. Fagunwa: A Commentary*. Ìbàdàn: Nelson Publishers Ltd.
Bámgbóṣé, A. (2007b). Symbolism in D.O. Fagunwa's Novels. *Modern Research Studies*, 1, 89-90.

Barber, K. (2017). *Celebrating D.O. Fágúnwà: Aspect of African and World Literary History*. Ìbàdàn: Bookcraft.
Bascom, W. (1969). *Ifá Divination: Communication between Gods and Men in West Africa*. Bloomington: Indiana University Press.
Beier, U. (1965). *The Yorùbá Novel: D.O. Fagunwa. In Introduction to African Literature*. Evanston, IL: Northwestern University Press.
Beier, U. (1967). *Yorùbá Poetry: An Introduction*. Cambridge: Cambridge University Press.
Délànọ̀, I.O. (1966). *Òwe Lẹṣin Ọ̀rọ̀*. Ìbàdàn: Oxford University Press.
Fágúnwà, D.O. (1938). *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀*. Lagos: CMS Bookshop.
Fágúnwà, D.O. (1949). *Igbó Olódùmarè*. London: Thomas Nelson.
Fágúnwà, D.O. (1949). *Ìrèké Oníbùdó*. London: Thomas Nelson.
Fágúnwà, D.O. (1954). *Ìrìnkèrindò Nínú Igbó Elégbèje*. London: Thomas Nelson.
Fágúnwà, D.O. (1961). *Àdììtú Olódùmarè*. London: Thomas Nelson.
Fálétí, A. (1970). *Ọmọ Olókùn Ẹṣin*. Ìbàdàn: Heinemann.
Finnegan, R. (1970). *Oral Literature in Africa*. Oxford: Oxford University Press.
Halliday, M.A.K. (1978). *Language as Social Semiotic*. London: Edward Arnold.
Irele, A. (1981). *The African Experience in Literature and Ideology*. Ìbàdàn: Heinemann.
Ìṣọ̀lá, A. (2009). *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Ìbàdàn: D.G. Mortoy Books.
Lindfors, B. (1982). *Critical Perspectives on Nigerian Literatures*. London: Heinemann.
Mieder, W. (2004). *Proverbs: A Handbook*. Westport: Greenwood Press.
Ojo, E.T. (2015). Structure of Proverbs in Selected Yorùbá Written Literature. *Ihafa: A Journal of African Studies*, 7(1) 161-191.
Òkédìjí, O. (1971). *Àgbàlagbà Akàn*. Ìbàdàn: Longman Nigeria Ltd.
Owólabí, K. (2001). *Essential of Yorùbá Grammar*. Ìbàdàn: University Press Plc.
Soyinka, W. (1968/2013/(Trans.) *Forest of a Thousand Daemons: A Hunter's Saga*. London/Ìbàdàn: Thomas Nelson and Sons/Bookcraft.
Unilag Stylistic Study (2015). A Stylistic Study of Proverbs and Idioms in the translated Novels of D.O. Fágúnwà.

## Bio's

**Prof. Raphael Ayọ̀ Adésuyan** is a distinguished scholar of Yorùbá linguistics and dialectology at the Department of Yoruba, Adeyemi Federal University of Education, Ondo, Nigeria. His research focuses on the morpho-syntactic and socio-cultural characteristics of Yoruba dialects, particularly the Ondo dialect, to enrich scholarly understanding of their forms and functions. Prof. Adesuyan has contributed significantly to the field through his publications on pronouns in the Ondo dialect and the creative use of language in Yorùbá proverbs.

**Ọ̀jọ̀gbọ́n Raphael Ayọ̀** Adésuyan jẹ́ onímọ̀ ẹ̀dá èdè Yorùbá àti ìmọ̀ nípa ẹ̀ka èdè ní Ẹ̀ka-Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá, ni Yunifásítì Olùkọ́ni tí Ìjọba Àpapọ̀ ní Adeyemi, Òǹdó, ní Orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ìwádìí rẹ̀ dá lórí àbùdá mọ́fọ́lọ́jì, ati gírámà, àti àṣà àwùjọ ẹ̀ka-èdè Yorùbá, pàápàá jù lọ ẹ̀ka-èdè Òǹdó. Ọ̀jọ̀gbọ́n Adesuyan ti ṣe àfikún ńlá sí ìmọ̀ nípasẹ̀ àwọn àpilẹ̀kọ rẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ nínú ẹ̀ka-èdè Òǹdó àti òwe Yorùbá.

**Dr. Taofiq Saadu**, Ph.D. in Yoruba Language and Literature from Obafemi Awolowo University, Ile-Ife, Nigeria, specializes in Yoruba oral poetry with a special interest in the poetry of Yoruba deities to shape cultural identity. As a lecturer at Adeyemi Federal University of Education, Ondo, and Deputy Director of Postgraduate Studies, he blends ancient wisdom with modern scholarship. With over two decades in broadcasting, he transforms Yoruba folklore into accessible media, promoting cultural preservation.

**Ọ̀mọ̀wé Taofiq Saadu**, tí ó kẹ́kọ̀ọ́ gboyè Ph.D. nínú Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá, láti Yunifásítì Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ tí ilé-Ifẹ̀ ní Orílẹ̀ èdè Nàíjíríà, ìwádìí rẹ̀ gbájúmọ́ ewì alohùn ajẹmọ́rìṣà Yorùbá láti mú ìgbòòrò bá àwùjọ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ni ní Yunifásítì Olùkọ́ni tí Ìjọba Àpapọ̀ ní Adeyemi, Òndó, àti igbákejì adarí fún ẹ̀ka ẹ̀kọ́ gíga, ó so ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ Yorùbá pọ̀ mọ́ ìmọ̀ ìwádìí òde òní. Pẹ̀lú irírí tí ó lé ní ogún ọdún nínú ìgbóhùn-sáfẹ́fẹ́, ó máa ń yí àwọn ìtàn àròsọ Yorùbá sí àwọn ètò tí ó rọrùn láti gbọ́ àti láti wò, báyìí ló ṣe ń gbé àṣà láruge.

Recebido em: 03/2026

Aceito em: 30/07/2026

**Para citar este texto (ABNT):** ADESUYAN Raphael Ayodeji, SA’ADU Taofiq. Ìlò òwe akọni d.o. Fágúnwà nínú ìwé ìtàn àròsọ *ògbójú ọdẹ nínú igbó irúnmọlẹ̀*. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), vol.6, nº Especial III, p.70-79, agosto 2026.

**To cite this text (APA):** Adesuyan Raphael Ayodeji; Sa’adu Taofiq (august 2026). Article title. Ìlò òwe akọni d.o. Fágúnwà nínú ìwé ìtàn àròsọ *ògbójú ọdẹ nínú igbó irúnmọlẹ̀*. Njinga & Sepé*: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 6 (Special III): 70-79.